


NJẸ O TI MURA TAN LATI PADE ỌLỌRUN?

Ibeere yi ni o ṣe pataki julọ fun ọ ni gbogbo aiye: NJẸ O TI MURA TAN LATI PADE ỌLỌRUN?

Ayọ rẹ tabi ibanujẹ rẹ titi aiyeraiye rọ pupọ mọ idahun ti o ba fi fun ibeere ti o ṣe pataki yi.

Emi ko bi ọ leere boya o jẹ ọmọ ijọ kan tabi omiran, bẹẹni emi ko si beere boya o ti ṣa ipa rẹ lati ṣe daada ni ile aiye, ṣugbọn, njẹ a ti tun ọ bi nipa gbigba Jesu Kristi gẹgẹbi Olugbala rẹ? Njẹ iwọ ti fi tọkantọkan fi gbogbo aiye rẹ le Oluwa lọwọ? Bi iwọ ko ba ti se eleyi, iwọ ko iti di ẹni igbala. O ti sọnu, o si nilati lo akoko oore-ọfẹ yi lati tọ Kristi lọ fun igbala.

Bibeli sọ fun wa wipe gbogbo enia ni ẹlẹṣẹ laiku ẹnikan silẹ: "gẹgẹbi a ti kọ ọ pe: ko si ẹniti iṣe olododo, rara, ko si ẹnikan" (Romu 3:10). O tun fi ye wa wipe niwọn igbati a ti jẹ ẹlẹṣẹ a ti da wa lẹbi iku. "Nitori iku li ere ẹṣẹ" (Romu 6:23) — iku yi ki iṣe iku ara lasan nikan ni, sugbọn iku ti ẹmi pẹlu. "Ẹṣẹ . . . ni imu iku wa" (Jakobu 1:15).

Kini ohun ti o tumọ si lati wipe enia jẹ ẹlẹṣẹ ti a da lẹbi iku? Ohun ti o tumọ si ni iyapa kuro lọdọ Ọlọrun ati kuro ninu ohun ti o dara ti o si wuni titi aiyeraiye. Otitọ ti o buru gbaa ni eyi.

Ọlọrun korira ẹṣẹ ati ọtẹ sibẹ O fẹran emi ati iwọ tobẹẹ ti O fi pese ọna asala fun wa. O fun wa ni Ọmọ Rẹ, Jesu Kristi lati jiya ati lati ku fun ẹṣẹ wa, gẹgẹbi aropo wa.

Jesu Kristi ko da ẹṣẹ kankan ri O gba lati gba ipo wa lori igi agbelebu. "On (Ọlọrun) ti fi I (Jesu) ṣe ẹṣẹ nitori wa, Ẹniti ko mọ ẹṣẹkẹṣẹ ri, ki awa le di ododo Ọlọrun ninu Rẹ" (2 Korinti 5:21).

Njẹ Ọlọrun nfi igbala fun ẹnikẹni bi? Bẹẹni. Jesu Kristi funra Rẹ wipe: "Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẹẹ gẹ, ti O fi Ọmọ bibi Rẹ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gba A gbọ ma ba ṣegbe, ṣugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" (Johanu 3:16). Ko si iyatọ, Ọlọrun fi igbala siwaju gbogbo enia. Ohun kan ti o nilati ṣe ni wipe ki o jẹwọ ẹṣẹ rẹ, ki o si kọ wọn silẹ, ki o si gba Jesu Kristi gẹgẹbi Oluwa ati Olugbala rẹ. Gba (gbẹkẹlẹ, simi le) ọrọ Ọlọrun gbọ wipe: "ẹjẹ Jesu Kristi, Ọmọ Rẹ (Ọlọrun) si nwẹ wa nu kuro ninu ẹṣẹ gbogbo" (1 Johanu 1:7). Bi o ti wu ki ẹṣẹ rẹ po to tabi ki o kere mọ, Ọlọrun ṣe tan lati dari gbogbo rẹ ji ọ, nitori O wipe: "Bi ẹṣẹ nyin ba ri bi ododo, nwọn o si fun bi ẹgbọn owu; bi nwọn pọn bi alaari, nwọn o dabi irun agutan" (Isaiah 1:18).

Maṣe lo akoko rẹ sofo lori ọrọ aiye yi nitori nwọn ki ipẹ fo lọ. Maṣe jẹ ki ipo rẹ ninu aiye tabi laarin awọn ọrẹ rẹ, ki o di ọ lọwọ lati gba igbala Ọlọrun. "Nitoripe ere kini o jẹ fun enia, bi o jere gbogbo aiye ti o si sọ ẹmi rẹ nu?" (Marku 8:36). Maṣe gbẹkẹrẹ le ijọ kan tabi eto kan, tabi ẹsin kan lati gba ọ la. Jesu Kristi nikan ni O le gba ọ la.

Bi mo ti ri — osi, are
Ija lode, ija ninu
Sọdọ Rẹ to le wẹ mi mọ —
Olugbala mo de, mo de.

Bi mo ti ri — 'Wọ o gba mi
'Wọ o gba mi tọwọ tẹsẹ
'Tori mo gba 'leri Rẹ gbọ —
Olugbala mo de, mo de.

Mo ni idaniloju wipe iwọ yi o gba Jesu Kristi gẹgẹbi Olugbala rẹ loni, ki iwọ si mura ta n lati pade Ọlọrun rẹ. Bi iwọ ba se bẹẹ, iwọ yi o ni alafia pipe ti o jẹ wipe On nikan ni O nfi funni.

Njẹ idi kankan le wa ti o fi yẹ ki o sọ ọrọ ti o ṣe pataki bi eleyi di ọla? Ọlọrun wipe: "Ẹ tẹtilelẹ, ki ẹ si wa sọdọ Mi, ẹ gbọ ọkan nyin yio si ye" (Isaiah 55:3). "Ẹ . . . ba Ọlọrun laja" (2 Korinti 5:20).

**Word Of Truth**, P.O Box 1126, Kaduna, Nigeria